IBADAN UNIVERSITY LIBRARY
12 DEC 1965
NATIONAL ORDINANCE

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLE   ORE AIYE TENI   GBOGBO LAWA

No 1,581 THURSDAY DECEMBER 9, 1965 (2D)

## Okunrin Kan Pa Ararẹ Si'nu Ile

IDI—ARABA:— Idaamu nla ba gbogbo awọn enia ti nwọn ngbe nomba 8 Ajegunlẹ Street Idi-Araba, Surulere, nigbati gbogbo awọn ara inu ile na ji ni kutukutu owurọ ana ọjọ Isẹgun ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ti nwọn si ri oku Ọkunrin kan ti nwọn jijọ ngbe inu ile na, Ọgbeni Fatolami Doba ti o ti ku bamubamu.

Ẹniti ọrọ na ṣe oju rẹ, ọkan ninu awọn enia ti nwọn ngbe inu ile na ṣe alaye fun Oniwe Irohin wa Ejongboro ti o lọ si ibẹ ni ana sọ wipe nigbati awọn ji ni owurọ ni awọn ba Ọgbẹni Doba nile, awọn si ṣe bi o nsun ni.

Ṣugbọn nigbati awọn ṣe akiyesi rẹ daada, ni awọn ri i wipe, ki iṣe wipe, o sun ni, ṣugbọn o ti ku bamubamu, ti ko si tun le mi mọ. Nigbana ni awọn to sunmọ ọdọ rẹ ti awọn si ṣe akiyesi rẹ daada, Awọn ri i wipe ọbẹ kekere kan wa nibiti o ku si, aake ilagi kan si tun wa nibẹ pelu.

Nigbati awọn wo ara rẹ lati mọ ohunti o paa, ni awọn ri i wipe o ti fi ọbẹ oloju meji kan ge ara rẹ lọrun, ti on na si sun ninu agbara ẹjẹ nibiti o ku si.

Lojukanna ni awọn ara inu ile na ti

WO OJU EWE KẸFA

### Ẹgbaa Mẹrin (8,000) Ọlọpa Ati Ṣọja Lọ Si Ibadan

# IPADE ILE-IGBIMỌ IJỌBA IWỌ ORUN BẸRẸ LONI

IBADAN:— Ni deede agogo mẹjọ kutukutu owurọ ana ọjọ ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi ni awọn ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati awọn Ọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti bẹrẹsi de si Ibadan lati oniruru ilu yika gbogbo Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria fun ipade ti awọn enia na yio ṣe ni owurọ yi.



Alhaji Adegbenro

Adele O'ori Ẹgbe Afẹnifere

Onirohin wa Ejongboro ti o lọ si Ibadan ni alẹ ana ṣe alaye fun wa ninu iwe ti o fi ranṣẹ si wa ni alẹ ana wipe lati irọlẹ ana ni awọn enia na ti bẹrẹsi maa de si Ibadan lati oniruru ilu ti awọn enia na ti wa.

Ṣugbọn o tun ṣe alaye pẹlu wipe, ọpọlọpọ ninu awọn ọmọ Ile Igbimọ na ni nwọn wa ni Ibadan tẹlẹ siwaju asiko yi.

Ohunti o mu awọn enia na ti nwọn fi wa si Ibadan siwaju asiko yi ni rogbodiyan ti o ti bẹrẹsi ṣẹlẹ yika gbogbo Ipinlẹ Iwọ Orun lati ọjọ ti nwọn ti dibo Ipinlẹ na tan.

Ọpọlọpọ ninu awọn ọmọ Ile Igbimọ na ni nwọn ti sakuro ni ilu wọn lati Igbati rogbodiyan ti bẹrẹsi ṣẹlẹ ni Ipinlẹ na ti nwọn ko si le gbe ile nitori awọn ọmọ ẹgbẹ Oselu ti nwọn nwa wọn kakiri. Nwọn ti dana sun ile awọn ẹlomiran nigbati nwọn wa wọn de ile wọn ti wọn ko ba wọn.

Onirohin wa tun fi ye wa ni alẹ ana wipe Alhaji Adegbenro, Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre lọ si ọdọ Ọlọla Fadahunsi, Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni irọlẹ ana awọn mejeji si jijọ sọrọ papọ fun nkan bi wakati meji ki nwọn to tuka.

Ṣugbọn nigbati nwọn pari ipade wọn na ni ana, nwọn ko sọ ohunti awọn jijọ sọrọ le lori fun awọn Oniwe Irohin ti nwọn parojọ si ẹnu ọna ile Gomina na lati gbọ ohunti nwọn nsọrọ le lori.

Nigbati nwọn pari ipade wọn na tan gbogbo awọn enia ti nwọn ba Alhaji Adegbenro lọ si ibi ipade na ni nwọn nrin ẹrin jade bọ lati inu ile ṣugbọn nwọn ko lati sọ ohunti nwọn sọrọ le lori fun gbogbo enia ti nwọn nduro de wọn ni ẹnu ọna.

Bakanna ẹwẹ, ni awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ na tun ṣe ipadẹ bonkẹlẹ kan ninu ile Oloye S. L. Akintọla, ni irọlẹ ana, awọn enia na ko gba awọn Oniwe Irohin ni aye lati wọ inu ile lọ lati gbọ ohunti nwọn nwọn nṣe ipade le lori, ṣugbọn awọn ti nwọn mọ daada nipa ọrọ ẹgbẹ Oṣelu ṣe alaye fun wa wipe nipa ipade ti nwọn fẹ ṣe ni owurọ yi ni awọn enia ṣe ipade le lori.

Ọkan ninu awọn enia ti nwọn jijọ ṣe ipade papọ ni ana sọ fun awọn enia ti nwọn lọ wadi lọdọ rẹ ohun ti nwọn sọ ninu ipade ti awọn enia ṣe wipe, on lero wipe Ijọba Apapọ ni awọn yio jijọ ṣe; ni Ipinle Iwọ Orun Naijiria.

A tun gbọ pẹlu wipe awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA ati Dẹmọ ni nwọn yio jijọ yan si aye awọn Minista nigbati nwọn ba ṣe ipade na ni oni nitoripe ẹgbẹ oṣela kan



Oloye S. L. Akintọla

Olori Ẹgbẹ Dẹmọ

paapa ẹgbẹ Dẹmọ ko le da Ijọba Iwọ Orun ṣe rara.

### Ofin Isede

Yika gbogbo Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni nwọn ko gbọdọ ṣe ipade gbangba ode nisisiyi, a fi awọn ti nwọn ba fẹ ṣe isin ati awọn iwasu ni Ijọba yio maa fun ni iwe aṣẹ ki nwọn to le ṣe isin iru yowu ti nwọn ba fẹ ṣe yika gbogbo Ipinlẹ Iwọ Orun.

Bakanna ni Ijọba ti tun ṣe Ofin wipe, ki Onile o gbele ni awọn agbegbe kan ni Eko, awọn agbegbe na ni Mushin' Ikẹja, Shomolu, Ajegunlẹ, Agege, Ajerọmi, Isọlọ, Oworonsoki ati Bariga.

A gbọ wipe ẹnikan ko tun gbọdọ jade ni awọn agbegbe na mọ lẹhin agogo meje alẹ titi di agogo meje owurọ ọjọ kẹrinla oṣu ti a wa ninu rẹ yi.

Onirohin wa tun ṣe alaye fun wa siwaju ninu ọrọ rẹ lati Ibadan ni alẹ ana wipe Apapọ Ijọba ti ko awọn Ṣọja ati awọn Ọlọpa lọ si Ibadan lati le lọ yika gbogbo inu ile ati gbangba ode Ile Igbimọ Aṣofin nibiti nwọn yio gbe ṣe ipade na ni owurọ yi.

Awọn Ọlọpa wọnyi ati awọn Ṣọja ti bẹrẹsi duro kaakiri gbogbo awọn adugbo kan ni Ibadan ni alẹ ana ti nwọn si tun to yika gbogbo iwaju Ile Igbimọ na nibiti nwọn yio gbe ṣe ipade ni owurọ yi.

A tun gbọ pẹlu wipe Apapọ Ijọba yio tun ko awọn Ọlọpa ati awọn Ṣọja lọ si Ipinlẹ Iwọ Orun lati Eko ati Kaduna ni owurọ yi ki wọn le lọ ṣe iranlọwọ fun awọn ti nwọn yio wa ni Ipinlẹ na siwaju asiko yi.

Gẹgẹbi alaye ti awọn Oniwe Irohin wa ṣe ni alẹ ana, a gbọ wipe awọn Ọlọpa ati awọn Ṣọja ti nwọn wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun nisisiyi ti le ni ẹgbaamẹrin (8, 000)

Gbogbo ohunti nwọn ba ṣe ninu Ile Igbimo na ni owurọ yi ni ẹ o maa ri ka ninu Iwe Irohin wa ni ọla ati awọn aworan pẹlu.

WO OJU EWE KẸFA



# ENIA MEJI TUN PADANU ẸMI WỌN NI ILESHA

ILESHA: Ni opin ọsẹ to kọja lọ yi ni enia meji tun padanu emi wọn lori rogbodiyan to tun nṣẹle nipa abayọri ibo si ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti o jẹ wipe ni ilu oshun ti ṣe ilu Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Oloye Joseph Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi ni awọn enia meji na ti padanu ẹmi wọn.

Irohin awọn ọlọpa fi ye wa lati ilu Ilesha pe awọn enia meji ti nwọn padanu ẹmi wọn na jẹ obinrin ati ọkunrin kan eyiti o jẹ wipẹ ninu ile awọn enia na ni awọn janduku ọmọ ẹgbẹ oṣelu ni ti lọ ba awọn enia meji na ti nwọn si sa wọn lada pẹlu awọn ohun ọṣẹ miran eyiti o jẹ wipe lẹsẹkẹsẹ na ni awọn enia meji na si ku.

Irohin na tun fi ye wa pe awọn enia ti awọn janduku ọmọ ẹgbẹ oṣelu na lo kọlu ni a gbọ wipe nwọn ko ti mọ ruko wọn ati awọn ọlọpa si ti gbe oku awọn enia na lọ si ile iwosan lakulaku ti ilu Oshogbo lati lọ ṣe ayẹwo wọn.

Oniwe irohin wa ti o wa ni ilu Ilesha tun fi ye wa ninu irohin rẹ pe ọpọlọpọ ile to jẹ wipe ti awọn Olori ẹgbẹ oṣelu kan ni awọn enia na si dana sun patapata eyiti a gbọ na si jona patapata.

Bakanna ni ọpọlọpọ awọn ile miran ti nwọn jẹ ti ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan ni a gbọ wipe awọn janduku ọmọ ẹgbẹ oselu kan si tun ba je kọja eyiti o jẹ wipe nwọn si le tete tun se

Oniwe irohin wa tun fi ye wa pe awọn janduku ọmọ ẹgbẹ oṣelu na tun kọlu ọga awọn ọlọpa ti o jẹ olori awọn ọlọpa ti nwọn kọ lọ si ilu nani awọn janduku na si tun kọlu ey ti ọjẹ pe lẹsẹkese ni nwọn yara gbe lo si ile iwosan ti Wesley Guild Hosptal ti ilu Ilesha lati lo ṣe itoju rẹ bayi

A gbo wipe awọn enia ti awọn ọlọpa ti mu bayi ti nwọn si ti ti won mọle ni Tesan won bay ni agbo wi pe nwon to adota enia

Irohin na tun fi ye wa pe nwon ti ko okeaimoye awon olopa ti nwon mo nipa ija lo si ilu na lati se ona bi eto alafia ati ifokanbale yio fi tete ṣe padabo si ilu na bayi

Oniwe irohin wa ti o wa ni ilu Ilesha tun fi ye wa ninu irohin re pe opolopo awon olori egbe ati awon omo egbe na to wa ni agbe gbe Ilesha lo je wipe nwon ti salo patapata bayi

**WANTED**

Advance Apprentice and Apprentice Printers.

Apply In Person
Irohin Imolẹ's Office
16, Bamgbose Street,
LAGOS.

## Ẹgbẹ Elepo Pupa ilu Ẹdẹ Fi Ake Ko'ri

ẸDẸ: –Awon egbe elepo pupa ilu Ẹdẹ ti fi aake kọri lori ofin titun kan ti Igbimọ Afunishọ Ijọba ibilẹ ṣe ni ojo Abamẹta ti iṣe ojo kẹrin oṣu yi pe ẹniti yio ba bta epo pupa ni ni agbegbe ilu Edẹ gbodo wa ninu ẹgbẹ Elepo pupa ilu Ẹdẹ ati agbegbe rẹ

Awọn Igbimọ Afunishọ sọ ninu ipade na pe, ẹniti kọ ba ti si ninu ẹgbẹ elopo pupa ko gbọdọ ta epo ninu ilu Ẹdẹ ati agbẹgbe rẹ mọ, alaga Igbimọ na Ọgbẹni Shitta Lawal sọ pe o di ti jwa awọn enia na lati ma a ṣe ifẹ inu wọn ti nwọn si taku pe awọn ko ni kini kan ṣe pẹlu ẹgbẹ ti nta epo pupa.

O tun sọ ninu ọrọ rẹ fun awọn igbimọ na pe, ẹniti ko ba ti ara mọ ofin ti nwọn ṣe yi, awọn ko ni kọ lati fi ofin ba oluwarẹ ja, a fi ki nwọn yara tete lọ jẹ ọmọ ẹgbẹ ẹlẹpo pupa ni kiakia

Irohin fi ye wa pe o le ni irinwo (400) awọn ti nkọ ẹyin ati ti nta epo pupa pe ki wọn tete fi ilu Ẹdẹ ati agbegbe rẹ silẹ ni kiakia, nitoripe nwon ko lati jẹ omo ẹgbẹ elepo pupa

Awon omo ẹgbẹ Itẹsiwaju ti sọ si ọrọ na ninu oro won ni a ti gbo pe nwon ni ogbon ti Igbimo Afunisho ilu Ẹde ndi lati sọ awon enia di omo ẹgbẹ Dẹmọ

Ẹgbẹ itẹsiwaju ni o ya awon lẹnu pe awon ti nwon fẹ le kuro ninu ilu Ẹdẹ ati agbegbe rẹ ti ngbe inẹ nisisiyi ti le ni adun mẹdogun

WO OJU EWE KARUN

# GBANJO!

NOVEMBER 15th — DECEMBER 15th 1965



Iwe itumo Ala,
Etutu Sise ise wiwo,
Ojo ibi Omo, ati
Ogun Ajebidan
3s 6d di 1s 6d

Iwe Afose Isedale
Yoruba ati Psalmu
Ajebidan.
3s 6d di 2s

Turari 2s 6d Pakẹti di 1/-

J. O. SHOYINKA P. O. Box 159 Mushin,

A le ri iwe wọnyi ra lọdọ :-
SHOYINKA ni 9, Iyalla Street, Mushin.

# Ọgọrọ Enia Kuro Ninu Ẹgbẹ Dẹmọ bọ si Ọlọpẹ

ADO-EKITI:- A gbọ yanu ni irohin kan ti o de ile iṣẹ wa ni ọjọ Ajẹ ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi jẹ nipbati Irohin na sọ pe, o lẹ 'ni ọọdun (300) awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ pẹlu iyawo ati ọrẹ wọn ni nwọn fi ibinu kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) bọ si ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Ipinlẹ Iwọ Orun ti nwọn si ṣe ipinnu pe, laiye lọrun awọn ko tun ni ṣe ẹgbẹ Dẹmọ mọ.

Lara wọn ni ọgbẹni Edward Ojo Abe. ẹniti o wọ ie fun ẹgbẹ Dẹmọ ninu Ibo ti nwọn di ni ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ni Ipinlẹ Iwọ Orun ninu ọdun yi, o ni on yọwọ yọsẹ tan patapata nin ẹgbẹ Dẹmọ, on si bọ si ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Ninu iwe ti ọgbẹni E. O. Abe, kọ si olori ẹgbẹ Dẹmọ Oloye Akintọla pe on fi ẹgbẹ na silẹ ni o ti ṣe alaiye pe, "mo gbe isisẹ yi ni igbọ ran si awọn enia mi lẹnu ti nwọn jẹ amugbalẹgbẹ fun ẹgbẹ Afẹnifẹre eyiti o jẹ pe lẹkan si mo tun di ọmọ ọmọ ẹgbẹ na.

Ọgbẹni Onafusi ti sọ pe, on ti yọwọ ninu igbimọ Ijọba ibilẹ Ilishin ninu iwe ti ọgbẹni Onafusi ko si akọwe igbimọ na ni o ti sọ pe, on ko ṣe ẹgbẹ Dẹmọ mọ nitori iwa madaru ati mago mago ti nwọn hu ninu ibo ti nwọn di ni ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ti dunyi nitorina okele gbigbẹ pẹlu alafia o san ju ile ti o kun fun ẹran pipa ti on ti ija lọ' on titun bọ sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre pada.

Ni Ijebu Ode ati Agọ Iwoye ni agbẹgbe Ijẹbu ni ọgbẹni J O Ogungbe ni on na ti sọ pe, on na ti yọwọ yọsẹ ninu ẹgbẹ Dẹmọ ti o si bọ sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre ninu ipade ti o pe awọn oniwe iroh n ni o ti sọ pe o le ni ọọdun (300) ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ni Agọ—Iwoye ti nwọn kuro ninu ẹgbẹ na ti nwọn bọ sinu egbe Afẹnifẹre, o ni awọn ni pe, egbe Demo kole muna do ko mo.

O si fi eda iwe na ranṣẹ si Oloye S L Akintọla pelu.

---

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS [Jan 22 Feb 20] Ireti si mbẹ fun ọ aya fi ki o lo gbogbo ọsẹ na pẹlu awọn ọrẹ ti ọ ṣtimọ rẹ ki o si ṣe ohun ti o wa ni ọkan rẹ lati ṣe,

PISCES (21 Mar 20) Alafia ara ko ni si fun ọ loni nirorina eyi ko ni jẹki ara rẹ ya si iya iṣẹ ṣiṣẹ ṣugbọn bi o ba le gbidanwo ti o si ṣiṣẹ alafia yio de si ọ.

ARIES (Mar 21 April 20] Ọpọlọpọ ire yio de si ọ lọsẹ yi tobẹ ti iwọ yio lo gbogbo ọsẹ yi gbadura larin awọn to fẹran rẹ iwọ si re orire:

TAURUS (April 21 May 20 O yẹ ki o ma lo ọgbọn ri re ninu ohunkohun ti o ba nṣe nitori ẹnikan wa ti yio ma ṣe ilara rẹ ti yio si ma jowu rẹ ki o ṣe pẹlẹ lọdọ oluwarẹ

GEMINI (Map 21 June 21) Ọpọlọpọ awon enia yio opob rikoto yi ọ ka loninlori ki o ma kiyesi ara niya iru ileri ti iwọ yio ma ṣe fun enia.

CANCER (June 22 July 22) Egbogi kan ti iwọ to yio dara fun ọ n lilo ki o si faramọ awọn ti o ba ri wipe nwọn jẹ rere si ọ

LEO (July 23 Aug 22) laika awon ire ti o wa pẹlu re si iwo ko le ṣe ki ara rẹ ma ṣe aisan tobẹ ti iwọ ko ni nitẹlorun si ire ti ọlorun fun ọ.

VIRGO(Aug 23 Sept 23) ire n iwo ti bẹ si ri lati ib rẹ yi ṣugbọn ko nṣe ọ gbogbo bi o duu,

LIBRA [Sept 24 Oct 23) Ọsẹ yi yio miringindi fun ọ to iwọ yio si ṣe oinie ti er okan rẹ ki o si ṣe suru nin mọ ẹ yi

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Ọsẹ yi yio dara fun ọpọlọpọ awọn ohun ti o gbalero ni yio ma jẹbẹ ohuun ti o si ngbe li ere yio di ohun arid inini si

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21] Ayipada si rer yio ṣele si ọ lara yi ṣugbọn ṣura ki ma ba ṣabo ohun nla kan ti o nro yio mi si siwaju

CAPRICON (Dec 22 Jan 21 Nitori ọkan rẹ ti ọ rọ rẹ yio mi ilẹsiwajo

---


## Ha Kini e eyi O




OGUN A PA YANMU—YANMU LORI ERIN MẸTA NI

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A ni O dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si da ra pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tu yara pa ayan ati idun

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si de wo, iwọ yio ri bi o ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọ ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu o ri erin mẹta yi ni nwọn mu un ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ati ile itaja kakiri orilẹ ede yi

DISTRIBUTORS
AMOS GBENLE & BROTHERS
34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS


---


BERE FUN OJULOWO ADI-ELEGBO

## "Congreve's Iodo Form—Ointment'



Atamatase ni egbog." ADI-ELEGBO" yi i fun itọju gbo bo oriṣiriṣi "EGBO—ẸSẸ" n k akia bi o ti wun ki jọ rẹ t le pẹ to, Adieiegbo yi ko ni ẹgbẹ nipa wipe awa ko idọ ti ii bi ẹri gbogbo ti o ba wa loja egbo patapata jade oju re yio su mo daradara. Lẹhinna oju egbo ti o ba jin sinu yio jẹ ni oju re ru wa soke, y o si pọn daradara run lakaru ko si mo wẹwẹre ni yio si sa ….

Alafia de si ọ niyen:

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won si isale iwe yi ni i gi e ranṣẹ lọ ra Bibeko awon Eleru tabi onijibiti ylo ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba r ra o;

Bere egbogi yi ni ṣobu awon:—

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.
WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street. Phone 22787

# Asọtẹlẹ Nipa Awọn Omo ti abi ninu Oṣu August 1965

Awọn ọmọ ti a bi ninu oṣu August 1966 ọdun ti a wa yi Iwonyi ni iru ẹya enia ti nwọn o jẹ nigbati nwọn ba di agbalagba Sọlọmon ọba Iresẹl sọ wipe kọ ọmọ rẹ ni ọna ti yi lo nigbati o wa ni ewe nitori nigbati o ba di agba tl apa ko ka mọ ki o ma ba ya kuro li oju ọna na ọmọ ti a bi larin ọjọ oṣu.

July 30 Aug 31 Yio jẹ iru ẹni ikan ti o fẹran iwa karimi kuku fẹtẹ rẹ yio si pọ ti yio ma na owo nitori ki a le mọ ye o mbe nibẹ ni onilu ti nki i bẹni alagbe yio ma kebosi rẹ tantan.

Aug 6—Aug 12: Yio jẹ omo ologbon, yio si kọ ẹkọ nibi ti o kbe ga yio si ka iwe rabi kewu de walala lina ogbon ori rẹ yio si po jojo.

Aug 13-Aug 19: Yio je ahun ati arire banijẹ ti ko jẹmu ti owo re wa, yio si je enit yio ma pon enia ati eleru.

Aug 20-Aug 26: Yio je enia ti o ni agbara karufi yio si sanra batakun yio si ni ikiml

Nigbati oṣu oju oruu ba di 15 ko dara ki enia bere aisan lojo y, bi enikan ba ṣe bọ ewu mbe nibẹ fun oluware Eyi je ojo 12 oṣu Sept 1965

Bi oṣu oju orun ba di 16 eyitl o bo si ayajo ojo 13 oṣu Sept 1965, ko dara fun enia lati lo ra oja fun tita nitori ko ni ri ere je lori re omo ti a ba si bi lojo yi yio je alainitiju

Omọ ti a ba bi ni ọjọ 14th oṣu Sept yio jẹ omo ti a ni lati fi agbara kọ ki o ma ba ya ago ko dara ki enia gbe Iyawo lojọ na fun ẹ iti o ba nf ẹmi g gun fun ara re ati fun obinrin rẹ pẹlu ẹniti o ba ra ọja fun tita yio padanu ọmo ti a ba bi nigbati oṣu oju orun ba di 18, eyiti o,

Bosi ayajo 15 osu Sept 1965 yio jẹ omo ti o ni igboya tio si je alakikanju pelu yio ri opolopo isoro ti adanwo nile aiye bi ọmọ na ba si je obinrin yio feran fari ati imototo yio si fẹran iṣẹ ṣiṣe yio si je eni owo la iwe titi digba ogbo re

## Lati Oju Ewe Keji

ati wipe awon eni na jẹ awon ti o wa lati pi ilu Ijẹbu tabi Urhaba.

Nwon wa kesi Igbimọ Afunishọ na pe ki nwọn ye ma a kona mọ awọn enia mọ eyiii o le ba oruko rare ilu Ẹpẹ jẹ nitoripe oro ti o delẹ yi ko jẹ mọ ti iṣelu rara.


## APIAS RHUMTC & DROGES

OJẹ ojulowo hanunhanun eghogi Jamani to lagbara gid fun Iwosan "LAKUREGBE" to mba enia ja

Orişirişi lakuregbe nl o wa lakuregbe Arungun ti o ma nsan enia ninu egungun ara lakuregbe ti o ma nwu enia ni ẹsẹ roboto ti o njẹki ẹsẹ wuwo lati ma rin Lakuregbe ti o ngbẹ orikerike danwo kori bi o tl rorun lati lo tabi ki o ma şe ayipada ẹsẹ, ara tita bi eyiti enia fi ata obẹ pa ibadi abi egugu ara wiwo, ako iba abi pipon tabi rirun.

Bi enia ko ba gbajumo lati t jẹ rẹ lasiko o le so owo pa enia



NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos

ATI NI ŞỌBU

IŞE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA IBADAN



## Angelina Super — Rose

(O TI LỌ WA JU)

Eleyi ṣẹṣẹ jade ni ko si nita rara aṣẹṣẹ jade akan a ko mọ ibiti o rlọ ohun pataki ti a mọ nipe "O ti lọ wa ju"

Super rose yi wa fun ipara gbogbo enia lọmọde lagba lọkunrin ati lobinrin o tun wa fun irun didi ati kiko olowu o nmu irun ọkunrin papa ma dan ki o si jọlo o ma fun ara nl ẹwa akotun awọ ara yio jẹ yọ jade perepere

Bi enia dudu ba loo yio ma dan gẹgẹbi jigi enia pupa agaga şe Iyen ti wa tẹlẹ.

Tere sare watabi ki o kọwe fun tirẹ loni ki o lo tan ni 'International osmetic Industries" 36' Ọmọwunmi Si jreet, lẹhin kanCu Mushin Ẹ tọju ara ati irun nyin ẹ tọ lu pẹlu awujẹsulọ nyia owo pọku ni 1/3d fun ẹyọ kan 5/- fun mejila ọmfun alaye si.



# Kere o Kere o! Akiyesi Pataki




Awa na le iẹri wipe Ojulowo hanunhanuu Egbogi ni LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ilẹ Naijiria

A wa na njẹwọ ni Igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba nl asiko yi ti nwọn fi şe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ sọya tabi pe ileri fun gbogbo awọn ti ami di tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbonsẹ deede, inurirun nigbakugba ara wiwo, Ẹsanri ẹhin didun sisan ati aiko riran kedere ko duro buruku ara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni ki ata'k ti nwọn nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ şe enia nipa sis di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla si'e mẹfa abọ (6/-6 pere Igo kekere şile mẹta abo (3/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ ni Şọbu awọn:—

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ORẸ AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,581 THURSDAY DECEMBER 9, 1965 (2D)


## Olori Egbẹ Afẹnifẹre Ni Ekun Akoko D'ologbe

IKARẸ – Ni kutukutu owurọ ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kejọ oṣu yi ni iro-hin de ile iṣẹ wa lati Ikarẹ ẹkun Akoko pe olori ẹgbẹ Afẹnifẹre fun ẹkun Akoko ati ọga agba ile ẹkọ kan ni ilu Ikarẹ ọgbẹni D. I. Bada ni a gbọ pe o jalaisi ninu ile rẹ ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kefa oṣu yi.

Gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ẹkun Akoko Ondo, Akurẹ, Ọwọ ati ni jakejado ilẹ Naijiria ati paapa ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni agbọ pe nwọn ti npesẹ si ile ọgbẹni Bada nigbati nwọn gbọ iṣẹlẹ pe ọgbẹni D. I. Bada ti jalaisi.

Irohin fi ye wa pe Adele aṣiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre Alhaji D. S. Adegbenro ti tẹ waya ibanikedun ranṣẹ si olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ẹkun Ọwọ ọgbẹni M. A. Ajasin lati ba on ki awọn ẹbi ologbe Bada eyiti Alhaji D S. Adegbenro tẹ waya ibanikẹdun loruko ara rẹ ati ti ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Oniwe irohin wa kan ran wa leti pe ologbe Bada lo gbe apoti ibo silẹ loruko ẹgbẹ Afẹnifẹre lati ba ọgbẹni Danieles Olumofin ọmọ Dẹmọ (NNDP) ni Iha Ariwa kini ti ilu Ọwọ fi agagbaga ninu idibo si ile Igbimọ aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti nwọn ṣe ni ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi.

# AWỌN ENIA KAN DANA SUN MỌTO MINISTA

ABẸOKUTA:– Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ karun oṣu yi ni awọn enia kan tun lọ kọlu mọto Minista alamojuto eto Iṣẹ fun apapọ Ijọba Naijiria ati olori ẹgbẹ Dẹmọ NNDP Oloye Adisa Akinloye ni Agọ-Ika, Abẹokuta eyiti o jẹ wipe awọn enia na tun dana sun mọto ayọkẹlẹ ti nwọn npe ni "Mercedes Benz" eyiti nọmba rẹ si jẹ WE 2025.

Onirohin wa ti iṣẹlẹ na ṣe oju rẹ fi ye wa pe Oloye Adisa Akinloye ko si ninu mọto nigbati awọn enia na lọ kọlu dirẹba to wa ninu mọto ayọkẹlẹ na ti nwọn si da duro ti awọn enia na si dana sun mọto na.

Ninu ọrọ dirẹba mọto na ọgbẹni Raimi Ọlayiwọla fun awọn ọlọpa ti Abẹokuta ni o ti ṣe alaye pe ko pẹ ti o da mọto na duro si Agọ-Ika lati yara ba enia kan sọrọ ni awọn enia na jade lati inu mọto ni iran eyiti awọn enia na si dana sun mọto na ti nwọn si tun le ọgbẹni Raimi kuro ninu mọto na ki nwọn to sun.

Ọgbẹni Raimi Layiwọla tun ṣe alaye pe on kosi mọ ẹnikankan ri ninu awọn enia ti nwọn ṣe iṣẹ ibi na.

Ọgbẹni Raimi Layiwọla tun ṣe alaye pe nigbati awọn enia to ngbe ni adugbo na ri ina to njo lati inu mọto na ni nwọn ba ke gbe eyiti gbogbo awọn enia fi sare de ibẹ ṣugbọn gbogbo ara mọto na lo ti jotan patapata ti ko ku nkankan ninu mọto na eyiti nwọn le tun ṣe lara mọto na.

Onirohin wa tun fi ye wa ninu irohin rẹ pe lẹsẹkẹsẹ na ni awọn ọlọpa ti yara de ibi ti mọto ayọkẹlẹ na ti njo eyiti ọga awọn ọlọpa ọgbẹni Amos Adeniyi ṣe jẹ ẹniti o ṣe aṣiwaju awọn ọlọpa to wa sibi ti ina nla na ti ṣẹlẹ ati pe ki awọn ọlọpa na to le pa ina na, gbogbo ara mọto na lo ti jo koja eyiti o le ṣe tunṣe.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa nipa iṣẹlẹ to ṣẹlẹ si mọto na pe nigbati on fi ọrọ jomitoro lẹnu ọga agba awọn ọlọpa fun ẹkun Abẹokuta ọgbẹni George Amu lori iṣẹlẹ na, ṣugbọn ọgbẹni Amu fi ye oniwe irohin wa pe nṣe ni awọn ọlọpa nṣe iwadi lori awọn enia ti o ṣe iṣẹ buburu ati pe ko ti si ẹnikankan ti awọn ọlọpa ri mu ninu awọn enia to dana sun mọto na.

## Ọkunrin Kan Pa Ara Rẹ Sinu Ile

LATI OJU EWE KINI

ranṣẹ si awọn Ọlọpa ni Surulere wipe ki nwọn wa wo ohunti awọn ri ninu ile awọn. Ko si pẹ pupọ lẹhin na ti awọn Ọlọpa na fi de ninu mọto wọn ti nwọn si wa wo oku Ọkunrin na ti nwọn si ba gbogbo awọn ohunti Ọkunrin na fi pa ara rẹ.

Ọkan ninu Ọga awọn Ọlọpa na sọ fun Ejongboro wipe, awọn lero wipe, awọn enia kan ni wọn wa pa Ọkunrin na sinu ile rẹ tabi ki o jẹ wipe Ọkunrin na lo pa ara rẹ, nitori idaamu ile aiye.

# Ipade Ile-Igbimọ Ijọba Bẹrẹ Loni

## Lati Oju Ewe Kini

Lati ana ti awọn Ọlọpa ati awọn Ṣọja ti de si Ibadan ni nwọn ti bẹrẹ si maa to kaakiri gbogbo igboro ilu Ibadan ti gbogbo awọn ara ilu si nworan wọn bi nwọn ti ṣe nṣe.

Irohin awọn Ọlọpa Ibadan fi ye wa ni ana wipe gbogbo awọn enia ti nwọn yio ba lọ si Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Iwọ Orun Naijiria ni owurọ yi ni awọn Ọlọpa ati awọn Ṣọja yio maa wo ara wọn ki nwọn to le fun wọn ni aye lati wọle lọ woran ninu Ile Igbimọ na wipe ki nwọn lo woran.

Bakanna ẹwẹ, ni awọn ọlọpa ati Ṣọja yio tun maa wo gbogbo aga awọn Ile Igbimọ na loni, awọn ọlọpa yio ma wo inu apo ẹwu ti nwọn yio wọ wọle, nwọn yio maa si fila wọn wo, nwọn yio maa wo inu bata ti nwọn ba wọ si ẹsẹ.

Bi awọn ba si ri ẹnikan ti o ba mu awọn nkan to lodi si ofin Ijọba lowo, nwọn yio mu oluwarẹ gẹgẹbi arufin.

A gbo wipe ohunti awọn ọlọpa yio maa ṣe nkan won yi fun ni wipe ki ẹnikan ma ba da ija silẹ ninu ile Igbimo na nigbati nwọn ba nṣe ipade ni owuro yi. ni iru eyiti nwon ṣe ninu odun 1962, ki apapo Ijoba to ṣe Ofin Pajawiri ninu odun na.

Bi iru rẹ ba si ṣẹlẹ ninu Ile Igbimọ na ni owurọ yi a tun jẹ wipe, Apapọ Ijọba Naijiria yio tun ṣe ofin pajawiri miran lẹhin eyiti nwọn ṣe ninu ọdun 1962, ki nwọn si tun dibo miran ninu ọdun ti nbọ yi.


## WANTED

Advance Apprentice and Apprentice Printers,

Apply In Person

Irohin Imọlẹ's Office

16, Bamgbose Street,

LAGOS.



Printed & Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45 Campbell Street Lagos. 9/12/65